OBA ADENIJI ADELE KEJI DI ASOJU EKO

# IROHIN YORUBA

Ẹgbẹ Oro Wa— "IWAJU L'OPA ẸBITI NRE SI"

## Akiyesi

Ti ẹ ba nkọwe si wa ki ẹ ma a kọ o yanju, ki a le tete ma a tẹ e jade fun nyin, eyiti ko ba yanju dele kole jade rara. Nitorina a tun tẹ ẹ mọ nyin leti daradara "Ẹ ma a kọ iwe nyin yanju o"

Olotu

AWON ARA IKIRUN SE AJOYO OMINIRA ; OMIDAN ABIOLA A. COLE DI IYAWO

VOL. IV NO 677 IBADAN, MONDAY, AUGUST 6, 1951. OWO IWE IROHIN YORUBA — KOBO KAN (1d)

### IFIHAN SI GBOGBO AGBAIYE

Li oju ala mi ọjọ kẹdogun oṣu April, 1951, mo ri i alagba kan to tọ mi wa, o nsọfun mi nipa ti aiye bayi pe iji kan yio ja eyiti ohun ije meje wa ninu rẹ:-

1. Inu gbigbona
2. Kuruna
3. Ṣopọna (yio ma yọ lara ọmọ enia)
4. Arun onigbameji
5. Inu rirun
6. Aiya didun ati ẹgbẹ didun
7. Oju didun

Nitorina ki olukuluku ọmọ enia gba awe ọjọ meje lati fi kepe Ẹlẹda rẹ.

Amos Ṣhogbanmu

## Ara Ikirun Se Ajoyo Ominira

IKIRUN—Lẹnu lọlọ yi ni awọn ara Ikirun ati awọn ara ilu agbegbe rẹ ṣe ajọ-pupọ fun idominira wọn ati fun iṣẹ ribiribi ti Ẹgbẹ Ifẹlodun nṣe. Ọrọ iwuri oriṣiriṣi ni nwọn sọ, nwọn si gbadura fun ilọsiwaju awọn ilu Enia Dudu.

Lẹhin na awon Ọba mẹrindinlogun ati awọn oṣelu ṣe ipade ojiji ni ile ijiroro, awọn ti wọn pe si tibẹ le ni ẹgbẹrun meji.

### Ẹ KU IRIN AJO O, ONILUFAAJI

Ni ọjọ kẹdogun oṣu kẹfa ọdun yi ni ọrẹ wa Ọgbẹni S. Ayanmuyiwa Ayandeji onilu-faaji kuro ni Accra Gold Coast lati wa ṣe ibẹwo ilu rẹ Ogbomosho.

Nigbati mbọ o ya ni Oshogbo, Ọgbẹni Gbadamosi Oyedemi (Aluṣekere) ni o gba a ni alejo, o ṣe e ni alejo pupọ. Ki Ọgbẹni Onilu-Faaji to kuro ni Oshogbo o lọ wo ẹjọ awọn Atinga pẹlu Alufa Ige ni Kotu Gannan (Assize Court) Oshogbo.

Alejo si pari ẹjọ na pe ọkunrin Alufa Ige nitori on ni o ṣe ..., na ni kuru ti ko fi di ija-igboro ni ilu Ogbomosho. Adajọ da silẹ o si gbe ... re fun un.

Lẹhin na ni o kọja si Ẹdẹ, Ọgbẹni Salawu Tola si gba a ni alejo. Ọgbẹni J Akano Ayano ni o gba a ni alejo ni ilu Ilobu. Ni Ibadan ni Ọgbẹni J Ọla Adigun ati Akinunde Ṣowunmi gba a ni alejo, nwọn nawo fun un ni ọpọlọpọ.

Nigbati o di 31/7/51 ni o wa ṣe ibẹwo ile iṣẹ Irohin Yoruba ni Eko, inu Olotu dun pupọ lati ri ati lati jọ sọ asọye pọ lori ilọsiwaju ilẹ wa. Nigbati o di ọjọ karun ti o ti de si Eko ni o ba kọja si ibujoko rẹ ni Accra Gold Coast. Alọ a dara, abọ asunwọn o, Ayanmuyiwa Onilu-Faaj. iwa ọwọn.



Alaiyeluwa Ọba Adeniji Adele II

Ẹniti ọpọlọpọ ilọsiwaju Eko wa ni asiko rẹ, on ati Oloye rẹ Onidajọ Bajulaiye ni yio jẹ aṣoju Eko lati ma a ṣe eto ati ofin awọn ilu ti iwọ orun Naijiria.

## Ọba Adele Ati Oloye Bajulaiye Di Asoju Eko

EKO—Ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni gbogbo awọn Oloye Eko ati Ọba Alaiyeluwa Adele Keji ati awọn enia pataki pataki bi Dọkita J Akanni Doherty, Lawyer S L Akintola, Ọgbẹni S L Ayẹni, J D Jawando, Ajọsẹ Adeogun, A A Ajibade ati Hadji Issa Williams pesẹ si Afin Ọba na ni ọsan, ni deede agogo kan.

Nigbati Igbakeji Ajẹlẹ Agba ti Eko de Iga Afin Ọba na awọn si fi han pe Alaiyeluwa Ọba Adele keji yio pẹlu awọn Alade ti yio ma ṣe eto ati ofin ti iwọ orun ti Naijeria. Nwọn si di ibo larin awọn Oloye Eleru Odibo, Oniru ati Bajulaiye. Ibo si mu Oloye Bajulaiye.

Ggbẹdu wa bẹrẹ si dun ninu Afin na, ayọ wa pọju. Irohin ko to amojuba. Lati ọsan ọjọ na titi di ọjọ keji ni awọn ara ilu fi njo. Adura wa ni pe ki Olodumare ko jẹki ẹmi Ọba gun, ki ilu tubọ roju, o. Olowo, o ku orire.

Ẹ ma a ka iwe Irohin Yoruba nlebagbogbo fun oriṣiriṣi iro n

## Omidan Abiola Cole Di Iyawo

EKO—Ni Ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kerindinlọgbọn oṣu to kọja lọ yi (July 26) ni Ọgbẹni Samuel Ayọdele Ajọ ti nṣiṣẹ ni "Lands and Survey Department" gbe Omidan Bernice Abiọla Abẹkẹ Cole ẹni ti o ti nṣiṣẹ ni "Service Press" ni iyawo, ni Ṣọọṣi St Peter. Alufa W R B Kuyẹ ni ẹniti o ṣe alakoso igbeyawo na.

Ogunlọgọ enia pataki pataki lo pejọ si ibi igbeyawo na. Iyawo na si fi jijẹ ati mimu tẹ wọn lọrun. Irohin ko to amojuba. Ọgbẹni Y Ayinla Disu sọ pupọ nipa iwa iyawo na pe ọmọluwabi ni, ati pe o jẹ ẹniti o fi ara balẹ ti o si le tọju iṣẹ rẹ pupọ. O fi han pe awọn ti jọ ṣiṣẹ pọ ri.

Adura wa ni pe ki Olodumare fi ibukun pupọ sinu igbeyawo na iṣẹ. o.

### AJODUN "EMPIRE-DAY" NI IGBOGILA

IGBOGILA—Ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu karun ọdun yi ni ara ilu yi ṣe ajọyọ Ajọdun Ijọba (Empire-Day) Ti ọdun yi ... ti Ijọba Egbado gba Igbogila layo lati da ti wọn ṣe.

Balẹ Igbogila ni o ṣe Alaga ... na, ti o ba wọ o bi o ti ... si ori aga ni ọjọ na, o ... Ọba Alade.

Awọn ọmọ ile iwe ti o ṣe ere oriṣiriṣi ni ọjọ na ni awọn Sikaatu Igbogila U N A School, Igbogila Methodist School, awọn Birigedi ọkunrin ati obinrin, ere wọn na pabambari, Irohin ko to amojuba.

A ki awọn Ọgbẹni Yesufu Asọgba ti Baptist Church Igbogila, Pupna Ọlọfin, Daniel Baakọlẹ, pẹlu Ọgbẹni J F Aniẹko ti o ... jijẹ ati mimu tẹ ọdidi enia mejilelogoji lọrun fun odidi ọjọ meje. Ki Oluwa jẹki ọdun ti mbọ ṣe oju ẹmi o.

## Asani Ojikutu Di Elewon

IBADAN—Laipẹ ọjọ yi ni Onidajọ W. J. Palmer ju Asani Ojikutu si ẹwọn oṣu kan tabi ko san pọun marun dipo ẹwọn na. Asani Ojikutu sọ fun awọn Ọlọpa pe Asiawu ati obinrin kan ti nje Folashade fọ ile on.

Ṣugbọn nigbati nwọn wa idi ọrọ rẹ, iro lo ja si. Agbẹjọro Ọladipọ Ọdunsi ni Asani Ojikutu gba, O si sa agbara pupọ lori ẹjọ na.

# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

IWE SI ALAṢẸ BODE-ỌBA
(Comptroller Of Customs)

Inu mi a dun pupọ ti ẹ ba le gba mi laye lati fi ọran ti o ndun gbogbo awa onisowo han Alaṣẹ Bode-Ọba (Comptroller of Customs) l'Eko.

Ohun ti mo fẹ fi siwaju Alaṣẹ Bode-Ọba na ni pe gbogbo ile ẹru (Customs Shed) ti o wa ni Bode-Ọba na ni a ti darugbo, gbogbo rẹ ni o si njo opolọpọ ẹru ni ojo na si nbajẹ, bẹẹ Ijọba ni lati gba owo wọn pe lori ẹru ti o ba ti wọle.

Nitorina a nfẹ atunse awọn ile ẹru (Customs Sheds) wọnyi, a si fẹ ki Alaṣẹ Bode-Ọba (Comtroller of Customs) papa gbiyanju lati ma yẹ awọn ile ẹru na wo ti ojo ba nrọ, ki o le mọ pe ọrọ mi ki iṣe irọ rara.

Ẹru ti ojo ba pa bẹẹ, adanu ni o jẹ fun awọn onisowo, nitoripe ti awọn oja wọnyi ko ba bajẹ patapata owo pọọku ni awọn a ta wọn. Nitorina a bẹ Alaṣẹ Bode-Ọba na ati Ijọba wa pe ki nwọn ba wa fi eyi si ero lati tete ṣe atunṣe na.

Ohun keji ti mo tun nfẹ akiyesi Oníbode (Comptroller of Customs) na fun ni wipe ki nwọn jẹki mọto ma a wọle ko ẹru gẹgẹbi nwọn ti nṣe tẹlẹtẹlẹ ri, nitori eto "one-way" ti nwọn ṣe ni ofin titun yi, adanu nla ni o jẹ fun onimọto.

Lati igbati nwọn ti da eto titun na silẹ, onimọto miran ko ni ri ẹru ko ju osi ponun kan lọ lojumọ, nitori inira ni lati wọle, ijangbọn ni lati jade, eyiti iba fi paara ẹmẹrin ko ni ri ayo kẹja ju ẹkan ṣoṣo lọ, bẹẹ Ijọba o gba owo "Licence" ti nwọn pe lori mọto kọkan ati owo "Third Party Insurance" ẹ o wa a ri pe adanu nla gba a ni fun onimọto nitorina a bẹ Ijọba ati "Comptroller of Customs" ki nwọn ba wa mojuto eyi na pẹlu o.

Mo dupẹ lọwọ Olotu fun aye ti ẹ gba mi yi. Ẹ ko ni ri ogun adanu o.

Emi ni,
Sammy Boy (Simple)

C/o J A Ajao Bros,
10, Egerton Road,
EKO


## Ẹ ma a polowo Ọja nyin sinu iwe "IROHIN YORUBA"

Ẹ o si ri iyatọ lario bi ẹ ti ti ni onibara si ati bi o ti tun bẹrẹ si ti ni si lati isisiyi lọ.



## Irora Lakuregbe

NIHIN NI IDẸRA GAN WA

Fun ibọkuro lọwọ lakuregbe o jẹ ohun pataki lati tun ohun to faa ṣe. Bi o ba ṣe pe idọti ara lo rogun si oju kanna, on nipe awọn erce (Kidneys) inu rẹ ti nwọn ni lati ṣe iranlọwọ lati sẹ awọn idọti yi kuro lora nwọn si nfẹ egbogi ti yio le mu wọn ṣiṣẹ daradara "De Witt's Pills" ni egbogi ti a ṣe gan fun on.

Nwọn ni agbara lati fọ awọn erce mọ de aye ti wọn ko fi ni bajẹ. Egbogi yi yio si fi wọn si aye iṣẹ wọn. Awọn erce na yio si ma a ṣiṣẹ deede pẹlu irọrun lati maa ti idọti jade.

De Witt's Pills jẹ egbogi ti nwọn ti lo kakiri aiye ti o si ṣiṣe iyọrisi rere pupọ. Ijẹri si i nipe awọn opolọpọ iwe iyin ni awọn enia ti nwọn ti ni irora lakuregbe ti fi ṣọwọ si wa lẹhin igbati nwọn ti lo egbogi yi ti wọn si ti ri pe iṣe rẹ dara.

Kini ṣe ti iwọ na ko fi ni tete loo fun aisan tirẹ? tete lọ suro raa loni.



De Witt's Pills

Jẹ egbogi pataki fun Ẹhin didun, Iwora, Lakuregbe, Arinka, Latanlatan, ati bẹẹbẹ lọ.

IJẸRI SI WA

Egbogi De Witt's Pills jẹ eyiti a ṣe pẹlu imọtoto ti gbogbo awọn eroja ti a fi ṣe o si jẹ pipe.



DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles





ABIYAMỌ ETI RE MELO!

Abiku ọmọ nda ọ l'ẹnu bi?
Awọn arun wọnyi ha nyọ ọmọ rẹ lẹnu bi.

AIPERI
ỌRẸRẸ
INU-IWO
OSI
IGBONA
IKỌ
IGBẸ-ỌRIN
OTUTU
IBA
JẸDIJẸDI

ati orisirisi awọn arun miran ti ima yọ ọmọde l'ẹnu ni igba EHIN HIHU, Lọ ra 'YARO' awo igba arun ọmọde ni fun gbogbo awọn arun ti ima yọ ọmọde l'enu.

"YARO" ko pa meji ni gbogbo ilẹ Nigeria.

Ki iwọ ki o ri pe oruko "YARO" ni o wa lara igo na ki a ma ba ta adamọdi egbogi miran fun ọ.



# J. A. Ajao & Brothers

GENERAL MERCHANTS
10, Egerton Road, Lagos, Nigeria

A nta awọn akan wọnyi— Iṣana orisirisi (Matches), Oogun Iyagbe (Epsom Salt), Kafura Pẹlẹbẹ (Camphor), Atike (Face Powder), Ọti Didun (Mineral Water), Cement, Bata Fanfan (White Canvas Shoes) Leather Shoes (orisirisi), Beer, Shnapps, Gin, Wine, Brandy.

## Medicine Stores

A tun nta awọn orisirisi ogun ni oke Ṣobu wa — Oogun Nararu iba, Atun-ẹjẹ-ṣe, Ikọ, Jẹdi-jẹdi, ati ogun fun Obinrin ati Okunrin Lakuregbe, Ehin Ọmọde.



## Abiyamo! "Bamwo" De!! Alajela Omode!!!




Idẹra ati alafia de! Ko si ibanujẹ ati aisun mọ. Angẹli olutọju ọmọ arẹ ti mu ẹbun kan wa fun u lati ọrun wa, "BAMWO" ni oruko ẹbun na. O dara pupọ fun Inu-iwọ, Iso tabi Igufe, Iba, Igbona, Eyi, Ailesun, Ibinu-sodi ati orisirisi aisan miran ti o ma nṣe ọmọde lakoko ehin hihu. Dan igo kan wo, iwọ yio si ri pe o dara ju eyikeyi ninu awọn ogun ti o ti nlo fun ọmọ rẹ lọ. Igo kekere 2s. 6d igo nla 4s. 6d. ọkọ 1/-.

# The

## Egba Trading Aradan Stores.

144, Denton Street, 18 Denton Bridge Street, P. O. Box 2, Ebute-Metta, Phone 569, A tun wa ni New Motor Park, Ogunpa Ibadan.

